# ARA EKO, AJ'OMOGBE MIRAN TUNDE O!





*AWOGBA Omode fun Girl, Eyi, Hiba-ekin, Orere. Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St., LAGOS*


# ELETI OFẸ

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO


*TO CLEAR*

*Gents Suede Court Shoe Brown, Black & Grey Before 50/- Now 42/6*

Obtainable at:-
A. B. AKINYEMI
*10A Moloney Bridge*
LAGOS


VOL. No. VIII 480. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, AUGUST, 11, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)

## Gambari Pa Filani Ko Lejo

Nigba kan ni Ikoyi Ile ni asiko igba aiye Ọba Olugbọn, awọn Hausa meji kan ba ara wọn ja lori okele ọka.

Ija na ṣẹlẹ nilu Kiṣi. Hausa kini jẹ Onidilali, ekeji jẹ ada ẹran jẹ awọn mejeji jijọ ra onjẹ, nwọn jẹun lọwọ, ẹnikini nsọrọ bi o ti njẹun, ẹnikeji njẹun niṣo. Nigbati eyiti nsọrọ ma wo ilẹ, awo ti mọ. Nibiti nwọn fa ọrọ na mọ ara wọn lọwọ ija de. Eyiti o nda ẹran fa ọbẹ oloju meji yọ, eyi Onidilali fa ida yọ laifa ọrọ gun, nwọn lu ara wọn, ẹnikan ku d'ọrun.

Ṣiga jẹ Balogun fun Olugbọn, lẹnu ala ilẹ rẹ si ni nkan nwọnyi gbe ṣẹlẹ. Bẹni Balogun Ṣiga ba sọ fun eyiti o pa enia wipe, ki o gbe oku ẹniti o pa re ki o si niṣo niwaju Olugbọn.

Olugbọn ti o ti mọ iru ẹya ti awọn enia na jẹ, o si mọ iru iwa ti nwọn le hu, bere lọwọ Hausa wipe, bawo ni ọrọ na ti jẹ, Hausa na nsọrọ, ko si ẹniti o gbọ itunmọ ohun to wi.

Nwọn ni ki Ṣiga tu ara oku na wo, nwọn ba ofifo ako ọbẹ eloju-meji, nwọn si tu ara Hausa wo, nwọn si ba ida ni ẹgbẹ rẹ. Nigbana ni nwọn wipe, Kabiyesi, Olugbọn, idi ọrọ na niyi, ekini ati ekeji wọn, ole ni wọn, Olugbọn si dahun wipe, ekini Gambari, ekeji Filani njẹ, bi Gambari ba pa Filani, ẹjọ ha mbẹ ninu rẹ bi? nitoripe ẹniti o yawọ ni Ogun ngbe, nwọn nfẹ ko ẹru ara wọn ni, kai, barawo! barawo!! barawo !!!.

Eyi na ni ohun ti o di owe, Yoruba ti nwọn npa bayi wipe, "Gambari pa Fulani ko lẹjọ ninu".

Yoruba a ma lo owe yi nigbati awọn igiripa meji, tabi, awọn Alagbara meji, tabi Ijoye meji, tabi Sanmọri meji, tabi Ọlọṣa meji ba jẹ ekeji niṣu, nwọn o ma wipe Gambari to pa Fulani ko lẹjọ ninu.


## THE NATIONAL BANK
## Of Nigeria Limited.

Ile ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ oniṣowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna a si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti anta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.
The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


## Aj'omogbe miran tunde o!

Ni ọjọ alamisi (Thursday) ọsẹ to kọja ni a gbọ iro-hin wipe awọn ọkunrin meji kan tun fẹ ji ọmọde-kunrin kan gbe l'ọsangangan ni Abule kan nitosi Apapa.

Awọn mejeji na jẹ ara ilu Ibo, nigbati ọwọ tẹ wọn, nwọn sọ fun awọn ọlọpa wipe iṣẹ Oniṣegun ni awọn nṣe, nwọn si ṣẹṣẹ de si Abule na laipẹ ni. Awọn Ọlọpa Ajegunlẹ fi wọn pamọ si Ṣọbu wọn.

Ọmọ ti awọn ẹlẹgiri meji yi jigbe na je ọmọ-ọdọ ninu ile No. 15 ni Balẹ Street, ni Abule Ajegunlẹ ni Apapa, oruko rẹ njẹ Kuranga Sumọnu baba rẹ mbẹ ni Ilọrin, ọmọ ọdun mẹwa ni ọmọde Kuranga na.

BAWO L'AṢIRI ṢE TU?

Ọgbẹni Jimọ Bello, alagba bi ọmọ adọta ọdun ti o ti nṣiṣẹ l'abẹ awọn Oyinbo Ọlọkọ Oju-omi (Elder Dempster Lines Ltd.) ri, ni ẹniti o joko siwaju ile rẹ ni 5, Fakunle Street, Ajegunlẹ ni ọsangangan ọjọ Alamisi ti o ri ọmọd kunrin kan ti o nsare lọ ti awọn janduku enia meji na nle lọ.

Wọn ti sare kọja nibiti Jimọ joko si ki nwọn to ki ọmọde na mọlẹ, nwọn si nfi agbara fa a lọ. Ọmọ na ko fẹ lọ ṣugbọn agbara rẹ kole bọ lọwọ wọn, ọmọ na wa kigbe wipe, "ẹ gbami o". Lẹsẹkẹsẹ ti Jimọ gbọ igbe ti ọmọ na ke yi, o fo dide, o sare lọ ba wọn, bẹni ọkan ninu awọn Oniṣegun na lọwọ bọ apo awọ to fi kọ'ra, o mu alangba-gbigbe kan jade, o si fi di ọmọ na l'apa mu, ọmọ na ko si le sọrọ mọ.

Nigbati Jimọ nlu ọmọ na mọ awọn lọwọ, ọkan ninu awọn aj'ọmọgbe na fi ẹsẹ fẹ, Jimọ kigbe pe awọn aladugbo ni awọn enia ba sare le, wọn si mu, nigbana ni nwọn ko awọn mejeji pẹlu ọmọ ti nwọn fẹ jilọ na lọ si ọdọ Balẹ Ajegunlẹ, ni nwọn wa ko wọn lọ si Ṣọbu awọn Ọlọpa. Nibẹ awọn Ọlọpa ti ko wọn si itimọle.

Awọn ọlọpa si mu ọmọ na lọ si Ile Alaisan (General Hospital) l'Eko fun ayẹwo. Lẹhinna na ni ọmọ to le sọrọ, o wipe oun ko mọ awọn ọkunrin mejeji na ri, oun ko si ba wọn pade ri.

Awọn aj'ọmọgbe mejeji mbẹ lọwọ ọlọpa nisisiyi. L'ọsẹ tokọja niti Lamidi Alabi ara Ilọrin, ti awọn ara ilu Ibo ni a tun ri yi o.



Aworan yi niti Alaiyeluwa Ọba Adeniji Adele Keji, Ọba wa na sọ wipe, on ati awọn Oloye on, ko f'aramọ Iwe Ayipada Ofin iṣelu ibilẹ.



Ẹniti a nwo yi ni Ọgbẹni O. A. F. Beyioku ti o nṣe Sẹkitẹri awọn Oṣiṣẹ Marine ni Apapa o mba ọkan ninu awọn Ogunna gbongbo ilu Ọba Sọrọ. Oyinbo na nwo Beyicku ninu aṣọ lesi ti o wọ. Gẹgẹbi ẹkẹko na ti jẹ igba otutu. Beyicku wọ ẹwu otutu tẹlẹ, o wọ Buba, o wọ Dansiki ki o to wọ agbada lesi le lori.



Aworan ti a nwo yi nitı Hillarn Katende ti o nṣe ayẹwo ọmọde kan gẹgẹbi iṣẹ rẹ bi oluranwọ iṣẹ Ile Iwosan, ninu Ile-ikọṣẹ egbogi ni o ti kọ iṣẹ rẹ nilu Nairobi.

Lẹrin-meji lọdun ni o ma nba Ajẹlẹ lọ si irin ajo ti nwọn yio si ṣe abẹwo ilelo bi mejileladọrin. Larin irin ajo wọn na, Katende yio ṣe itọju awọn ẹnia to le si Ọkẹ-meji ti aisan nṣe ki nwọn to pada wa sile.

## Emiabata Sin Omo Meji Niyawo

EKO. Ọgbẹni Lawani Ẹmiabata ti o nṣe aṣoju fun iwe irohin Eleti Ọfẹ nilu Atan ni agbegbe ilu Ọtta. sin ọmọ meji niyawo lọjọ kanna. Ọkan ni Ita Akanni ati ekeji ni opopo Victoria.

Orukọ iyawo ti Ita Akanni ni Sikira Agbekẹ. Ero pọ bi omi, diẹ ninu awọn gbajumọ ti o wa sibi iyawo na ni nwọnyi.

Amusa Gbadamọsi, Iya Afin Mọrẹrikẹ Bankọle, L. Ẹmiabata, Adetohun Sanni, Alufa Karaole, Mọmọdu Balogun, Tẹsi Alufa, Sadiku Abudu, Rafatu, ati Ọkọ iyawo ti Opopo Victoria ni Abudu Karimu. Awọn gbajumọ to wa sibẹ ni Ọgbẹni L. Alabi, Alufa Karaole, Mọmọdu Balogun, Baba Ọwọ, Tẹsi Alufa, Salami Sanusi, Sadiku, Hadji Imam Bakare, Sala Adukẹ.

Malu kọkan ni nwọn pa, Lawani Alabi ati Momọdu Balogun nawo-nọra. Owotiẹna ko ni gbe, owo a ba nyin na, ọmọ a ba nyin jẹ, iyawo a tọwọ bọ osun, bi oluwa ba fẹ.

## Oluwadi Ko Temilorun— Azikiwe

ENUGU Ninu Ile Igbimọ Ila Orun ti nwọn ṣe lọ yi Prime Minister agbegbe Ila Orun sọ wipe Adajọ agba to mbẹ nilu Eko ẹniti ijọba Gẹsi yan lati ṣe oluwadi nipa ọrọ ẹlọ Continental Bank, ko tẹ on lọrun. Ninu igbimọ ti nwọn ṣe lọ yi ni Ila Orun, nwọn pinnu wipe adajọ agba ninu koto giga ilu Oyinbo ni on fẹ ki o wa ṣe alaga iwadi ọrọ na. ki a si yan awọn isọngbe rẹ larin awọn ti ko si labẹ ijọba ilu Gẹsi.

Azikiwe sọ wipe, on ko fẹ ki a yan Jibowu, nitoripe o ni mimọ nipa bi ọrọ ti nlọ si nilẹ Nigeria, bakanna ni gbogbo awọn oluwadi ti Sẹkitẹri ilu ọba yan.

Ọrọ ti nwọn tun sọ ni wipe, awọn nfẹ sọ fun ijọba ilu Eko wipe, ki a yan oluwadi lati wadi nipa B. B. W. A. Ltd. ekeji ni wipe Azikiwe pitan nipa B. B. W. A. ati National Bank. Eyi nibiti a ba ọrọ Banki na de. Bi ọrọ ba si ti nlọ ẹ o ma gbọ.

DECCA
RECORDS

A. G. LEVENTIS & CO. LTD.
are pleased to announce that they have been appointed distributors for
DECCA
GRAMOPHONE RECORDS
& High Fidelity Reproducers
Tel. 20291, 20129, 20120, 20127, and 20128.

## Isinmi dara lehin ise



IBADAN- A gbọ wipe Oloye Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ yio gba aye isinmi oşu meji kuro lẹnu işẹ, yio si lo gbogbo akoko isinmi rẹ na nilẹ Nigeria.

Bi o ba lọ tan, Oloye Ọlọla Rotimi Williams ni yio dele de e, o si ti fi aşẹ le e lọwọ. Alọ yio dara, abọ yio suwọn.

## Alhaji Akanbi ku si Meka

ILỌRIN. Anu şe ni gidigidi lati gbọ wipe Alhadji Akanbi Ilọrin ku si Mẹka.

Gẹgẹbi a ti gbọ ọrọ na si ni wipe, Alhaji Akanbi jijọ ba awọn ero Mẹka de Karitum, nwọn jijọ gbe Ihiram, nwọn jijọ de ori oke Arafa, nwọn si jijọ gun ori oke Mina nwọn jijọ mu omi Zẹmzẹm.

Nwọn lọ si Mẹdina, nwọn si lọ si Siara sare Anobi Muhamad, nwọn ti pari işẹ tan, Nibiti nwọn ngbaradi lati ma bọ wa sile ibẹ ni ọlọjo gbe desi. Ọlọrun ko f ri i i.

Eleti-Ọfẹ d'araba, gbogbo enia lo nsure ra, ẹ ma ka lọsọsẹ, o kun fun ẹkọ ati Ọgbọn.

No. 73/S2/VOL.VII/221.

## Government Teacher Training College. Ibadan. Admissions 1957.

1. There will be vacancies for three new classes at this College in January 1957 to undertake a Two Year Course leading to the Teachers' Certificate Grade II:-
   (a) For Teachers with a Teachers' Certificate Grade III who have taught for two years since finally passing the Teachers' Certificate Grade III examination.
   (b) For applicants who:-
   (i) Already possess a Cambridge School Certificate.
   or
   (ii) Are in the final year of the course at an approved Secondary School and who will be sitting for the Cambridge School Certificate Examination or West Afican School Certificate Examination in this year.
2. All applications must be submitted through sponsors.
   Sponsors may be the following:-
   Local Authorities
   Voluntary Agencies without Grade II training facilities.
   Proprietors of Secondary Grammar School.
   All private applications will be ignored.
3. Sponsors will be responsible for paying the fees of £15-0-0d per year.
4. An allowance (at present £36) will be paid to candidates selected for the School Certificate Class, and on the successful completion of the Course they will rank as "Pivotal Teachers".
5. Teachers with Grade II Certificates will continue to draw their salaries less a deduction of £24 for Board etc.
6. The Entrance Tests and interviews will be held:-
   (a) For Teachers with a Grade III Certificate on 31st August and 1st September, 1956.
   (b) For the School Certificate Class on 3rd November, 1956.
7. When names are submitted by sponsors, Entry Forms will be provided. Completed form in respect of Grade III Certificated teachers must reach me not later than 25th August and in case of Cambridge School Certificate holders not later than September 30th.

(Sgd.) J. E. Williams
Ag. Principal,
Government Teacher Training College.

## Talaka Parapo bori ni adugbo Ajikobi

ILỌRIN. Ninu ibo ti nwọn di ni adugbo Balogun Ajikobi, ibi kan lo ku ti nwọn yio dibo, nigbogbo adugbo na, ẹgdẹ Talaka-parapọ mẹtalelogun lo si wọle, ti ẹgdẹ N. P. C. jẹ meji.

Ni Alanamu, gẹgẹbi a ti sọ lọsẹ to kọja lọ lọhun ẹgbẹ Talaka-parapọ lo wọle pupọju ati wipe ni adugbo meji nwọn yi, ni awọn enia pọ si ju.

Asi tun gbọ wipe ninu gbogbo ibo ti nwọn ndi kakiri na, ẹgbẹ Talaka parapọ lo şi ngba iwaju.

## Ipade L'ori Rogbodiyan Ito Suesi

LONDON— Awọn ilu orilẹ-ede alagbara mẹrinlelogun yio şe ipade apero lori ọrọ Itọ Odo ti a npe ni Suez Canal to fẹ da ijọngbọn silẹ l'arin wọn pẹlu ilẹ Mọsari (Egypt) nisisiyi.

Awọn ilu ti yio peju-pesẹ sinu ipade na ni ilu nla London ni awọn ilu bi:- Australia, Ceylon, Denmark, Ethiopia, East Germany, Greece, India, Indonesia, Persia, Japan, New Zealand, Norway, Pakistan, Portugal, Sweden ati ilu Amerika ni Ọjọ kẹrindinlogun oşu yi.

Ki apero wọn yọri si rere ni adura tiwa.

## Eke Pa Eleke Odale Pa Odale

ILỌRIN. Ọdọmọkunrin kan ti o wa lati Abule Onigambari, bẹrẹ si pidan larin ọja, o nfi ọbẹ yọ oju ara rẹ, şugbọn oju na ko yọ, ni were-were, awọn enia ti şuru bo o lati wa woran.

Ọkunrin na ti a npe ni Mọmọ bẹrẹ si pa orişirişi idan tobẹ ti ariwo ta, ti awọn ọmọde si nho ge-e-e, ka npatẹwọ.

Nigbati o şe ni okunrin na ba fa ọbẹ kan olori şonşo yọ, o si fi gun ara rẹ ni agbẹdu nşe ni ifun rẹ tu jade. Awọn to duro ti o nworan kokọ tete şakiyesi ohun ti o şẹlẹ, nwọn nho, nwọn npatẹwọ.

Şugbọn nigbati ẹjẹ pọ, ti ọkunrin na si şubu lulẹ, o di igbẹ l'a nfẹ'we, oko l'a nfẹ'ewe'bẹ ọlọmọ gan ọmọ rẹ lapa, o di bi o ko lọ ya go fun mi. Asẹhin wa, asẹhin bọ ọkunrin na ku.

Eke ni yio pa eleke, Odalẹ ni yio pa ọdalẹ, lo difa fun Amọkun şọle to pe ọba aiye ko ri on, bi ọba aiye ko ri ọ, t'ọrun nwo ọ.

# ELETI ỌFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAMS

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - ỌFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. VIII. NO. 480, LAGOS, SATURDAY AUG 11., 1956.


## SURU L'EBO

Irohin ti a gbọ nipa owo Koko ti o tun dinku si eyiti a ti nk'igbe wipe owo tita Koko wa nlọ silẹ nigbati awọn sọ di igba poun (£200) fun Tonun kan, ti awọn ọlọkọ ijọba Iwọ-Orun si sa agbara, ti nwọn ko fi jẹki awọn agbe, onisẹ ohun ọgbin Koko mọ inira ẹdinwo to wa l'ori tita Koko fun wọn ni ilẹ awọn Oyinbo.

K'ari, k'atnnri ni ikede ti a ri ka wipe owo tita Koko yio tun mirehin di adọjọ pọun (£150) fun Tọnun kan ni ọdun yi, yio jẹ ohun iyalẹnu fun ẹlomiran ṣugbọn awọn ti oye rẹ ba ye si dara-dara yio mọ wipe, eyi ko le ṣai ri bẹ nitoripe orişirişi ilu ni Koko ti njade nisisiyi ti o jẹ wipe eyiti awọn to nlo Koko ti ri silẹ kojẹ ki nwọn nani Koko tuntun to şeşe jade dabi ara.

Ope ni fun awọn Ijọba wa ti o da ile Ita'ja silẹ (Marketing Board) ti awọn igbimọ rẹ si fi tọkantọkan bojuto işe oja tita ilẹ wa de'po ti nwọn tun fi nlo Owo girimọvan fi şe ẹkun owo tita Koko wa fun awọn Agbẹ ti ko jẹki adanu wọn f'arahan.

O yẹ ki awọn Agbẹ Onişẹ ohun ọgbin Koko mọ daju wipe "Olu ẹ i ni ina ko tan owo" bi awọn ta ... aradara, a ri pe "Ọrun mawo ni, ki işe ... ẹ" awọn Agbẹ ilu Aganyin (Gold Coast) ti ... eb'ina ti o fẹrẹ ju eyi lọ, iba ohun ti o wa nibẹ ni ki a fişe ọgbọn, lati le mọ ọna ti ao fi maşe atu şe ohun oja tita wa ati alekun orişi ọja miran ti a ko ti ni gbekẹlẹ Koko nikan.

Gẹẹ i gbogbo akan, papa işẹ owo tabi ọja tita ati rira ti ma nlọ niyẹn, o tun le yipada ki owo tun g'ori Koko ni ayida miran, ki awọn agbẹ wa fi suru si.

SURU LẸBỌ.


## ABOKI



JẸ AWOGBARUN to LOKIKI KA ILẸ ENIA DUDU.
AJẸBIDAN ni fun IKỌ, LAKUREGBE, IWORA, AKOKORO, SOBIA, AKANDUN, JẸDIJẸDI, etc.

KOŞEFẸKU ni GBOGBONŞE yi jẹ fun GBOGBO ILE nitorina RA IGO kan LONI Lọdọ:-

IBUKUN - OLU MEDICINE STORES,

Amunigun Street, Box 245, Phone 189x, IBADAN

E 21, Sabongari, ZARIA, X 5, Central Market, Box 2205, Kumasi, Gold Coast.


## Itiju pa mi, are epe.

PORT - HARCOURT.

Awọn Yoruba lo npa owe bayi wipe. "Agbalagba ko nşe langba-langba, itiju pa mi arẹ epe". Ọgbẹni Adelabu ti nwọn npe ni enia nilẹ Yoruba ti awọn ẹgbẹ N.C.N.C. npe l'enia nihin, ni agbọ wipe, o tẹ ko dun'bẹ nilu awọn Ibo lọhun.

Adelabu rope, gbigbe ti awọn Ibo ngbe on gẹgẹ nihin, ko mọ wipe nşe ni nwọn ngbe on gun Ayan o rope ni wọn igbati awọn diẹ kan ti nfẹran on yẹn, nitorina gbogbo nwọn ni o nfẹran on.

A gbọ wipe o de ilu Portharcourt abuku ni nwọn fi kan a, Mayor ilu na sọ pe, on ko mọ ẹni'i nwọn npe ni Adelabu, ati pe on ko gbọ telẹ pe ẹnikan ti a npe ni Adelabu mbọwa.

Şugbọn patapata kọ ni Ajapa ko niru awọn mọto mẹrin lo lọ pade rẹ pẹlu awọn obinrin bi melo kan.

## Ayipada Iwe Ofin Eto Iselu-Ibile Eko 1956

Ninu ipade pataki ti awọn aşoju ilu Eko şe ni Alaga igbimọ Ọgbẹni A.O. Lawson ti fi alaye siwaju awọn igbimọ l'ori ayipada Ofin eto işelu-Ibilẹ ti ilu Eko ti awọn Ọlọla Alabojuto ilu Eko şe siwaju igbimọ apapọ ti ijọba lati f'aşẹ le.

Ọpọlọpọ ayipada ti nwọn nfẹ şe na ni ko tọ suna, papa nwọn ko tilẹ ro si ẹtọ l'ati fi eto ayipada na han awọn igbimọ ibilẹ ilu Eko ki nwọn to şe awọn ayipada na eyiti o jẹ wipe yio fa ilọsiwaju wa s'ẹhin yatọ si awọn ilu yoku to wa ninu Apapọse ijọba Nigeria.

Ekini ninu ayipada na ni ti awọn Oloye to wa ninu igbimọ ti o jẹ mẹjọ ki o di mẹrin pere, bi iru eyi yio ba tilẹ şe, Ọba ilu Eko awọn igbimọ rẹ l'o ni ẹtọ lati şe bẹ, şugbọn ako ro wipe nwọn fi eto na han Ọba ati awọn Oloye rẹ.

Gẹgẹbi agbọsọ ọrọ ti a ma ngbọ wipe awọn Oloye Eko ko f'aramọ ẹgbẹ N.C.N.C. ni ohun ti o mu wọn fẹ şe adinku awọn Ijoye to wa ninu igbimọ ibilẹ ni o, ko ye wa.

Ọpọlọpọ eto ti a fi nşe işẹ tẹlẹri to fi kan ti owo igbimọ ibilẹ ni nwọn fẹ şe ayipada rẹ. Lori eto yi ni a şe fi alaye tiwa ranşẹ si Akọwe agba ti ijọba apapọ ati gbogbo awọn Ọlọla to mbẹ ninu ile igbimọ Apapọ ti ilu Eko ati awọn Oniwe irohin.


## OPEN TO PUBLIC

**LAFIA REST HOUSE**

**Near Moor Plantation, Ibadan**

**Air-Conditioned & Ordinary Suites**

Available at reasonable prices

**Licensed Bar, Dining Room** and Lounge

**Open to Non-Residents**

**Parties Catered For**

on and off premises

**Special Lunches & Dinners**

by arrangements.

(PHONE: IBADAN 345)

WESTERN REGION PRODUCTION DEVELOPMENT BOARD.

## Egbe Omo Ife Eko se Bebe.

EKO. Irohin koto afojuba ni aṣeyẹ ti awọn ẹgbẹ ọmọ Ifẹ Eko ṣe nibi ariya Igbeyawo ọmọ Madam Ayinkẹ Ọlagbaju ni gbangba 59, Okepopo Street, L'eko ni ọjọ Sunday 5/8/56.

Ni inkan bi agogo meji ọsan ni ẹsẹ t'ọmọde ta'gba wọn gun regerege ninu aṣọ t'oto aṣọ ti ẹnikọkan wọn wọ, kini Ayinkẹ Ọlagbaju f'oju kan awọn ẹgbẹ yi si, lẹsẹkẹsẹ ni o ti pese ijoko, ni, ki nwọn to fidi lelẹ tan, ni jijẹ ati mimu ti nkọlu ara wọn ni ọkan-ko-jọ-kan, lẹhin jijẹ ati mimu ni Ayinkẹ papa wa bọsi agbo ijo, ti tọ'mọde-ta'gba ẹgbẹ yi bẹrẹ si fi owo t'oto owo yẹ ẹ si, ti awọn na tun n'ba ran l'agbo-ijo bi okoto ti ilẹ ọjọ na fi ṣu.

A kole ṣalai ma darukọ diẹ ninu awọn ọmọ Ifẹ ti awọn peju sibi ariya ọjọ na awọn ni awọn Iya wa bi:—Wulemọtu Langunna, Asimọwu Bandefẹ, Aṣia Iga-Faji, Adedunla, Barikisu Araloyin, Buṣura Awoyejọ, Titilọla Thomas, awọn Ọgbẹni Rufai Giwa Awoyejọ, Y. B. Ọbasa. A. K. Ọbasa, Alli Aiyedun, Imam Adetoro, Adisa Shekoni, Abasi Igẹdi, R. B. Thompson, Yẹkinni Badabiyu, Rabiu Ọbasa, Ọmọ - Ọba Adesiran Adefarakan ati ọpọlọpọ gbajumọ ọmọ Ifẹ ti aye ko gba wa lati darukọ wọn tan nihin.

Ọmọ Ifẹ Eko, eyi wun wa o. Ire a kari o.

## ODUN IPILE

15th OGUN AUGUST. 1956.

Li Agbara Oduduwa, AJỌDUN ẸLA ỌDỌDUN li a o ṣe yika Ilẹ KARỌ OJIRE ati ni ayika rẹ ati yikayika Ilẹ wa, ni Ọjọ'ru 15th Oṣu Ogun-August, 1956.

A o si ṣe aisun ni alẹ Ọjọ Iṣẹgun 14th Oṣu Ogun-August, 1956. Aiṣun yi yio bẹrẹ ni agogo mẹwa gan, ni "ILE IJUBA" gbogbo.

Ẹbẹ pataki li a o ṣe karakara fun IGBADUN IBALẸ ỌKAN ati ỌRẸ ODODO ni Orilẹ Ede wa ati kakiri Ayika Aiye li akoko ewu yi.

(G. A. DOSUMU)
AKỌWE GBOGBO-GBO
AJỌ BABALAWO NIGERIA

## Okunrin kan pe Dereba Reluwe lejo

Lọjọ kan bi Reluwe kan ti nsare lọ loju irin, gẹrẹ ni ese rẹ yọ, o kọri si papa, o si lọ pa malu kan.

Lẹhin ti egbe-regbe ti egbe-regbe ni Agbọ to ni malu, eyiti reluwe na pa wa lọ pe ejọ pe on fẹ gba owo malu ti reluwe pa.

Adajọ pe derẹba ti o wa ọkọ lọjọ na jade, lọya wa mbere lọwọ rẹ wipe:-

Lọya—Wo mi na, Derẹba, njẹ oju irin ni malu na wa ki ọkọ to pa a ndan?.

Derẹba—Rara! Ninu papa lo wa ti o njẹ koriko, lojiji ni reluwe fo ọgba da, o sọlu igi, o si ba tegbo-tegbo ki o to lọ pa malu na ni bi ti o njẹ koriko, o si pa a sibẹ.

Bi ọrọ na ti lọ niyi, a fẹ ki ẹnyin Ọkawe wa ṣe idajọ na, talo jẹbi, ati bawo lo ṣe jẹbi.

## Awon to ba Alafin s'eye igbade ni Bara.

OYO. Nigbati Bello Gbadagesin fi jọba ilu Ọyọ, O lọ gbade ni Bara. Lẹhin ti o gbade na tan, gbogbo awọn ijoye ti o wa lati orisirisi ilu gbogbo wa bẹrẹ si lọ kerufu.

Diẹ ninu awọn ilu to lọ ba ọba ṣe ayẹsi ti igbade lọjọ na ni, Ijoye Awẹ, Abẹokuta, Akinmọrin, Ogbomọṣọ, Eko, Ibadan, Ijẹbu, Epọ ati bẹbẹ.

Orukọ awọn enia pataki ti o lọ ba wọn ṣe aṣeyẹ na ni. Dokita Maja, Eleru Odibo, T. S. Fuja Onilẹgbalẹ, J. A. Ajao Ọtun Ọyọ, T. Fadina, Sanni Adele ati Ọgbẹni p. A. Soares, Baṣọrun Ọyọ, ati awọn Ọyọmisi enia pọ bi omi l'ọjọ Satide na.


**Kere o!**

A ti ni origirisi ogun Germany to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos


## OBINRIN KAN DI ORI EJO MU

Obinrin adelebọ kan ti o ngbe abule kan lo ko ẹran pamọ si iyara ibi ti nwọn nko awọn ohun elo ọbẹ pamọ si. Ni ọjọ keji o lọ sinu iyara na lati ko awọn ẹran ti o fi pamọ lana jade.

Bi o ti tọwọ bọ ago ibiti ẹran na gbọ wa ori ejo lo dani. Obinrin na ko le ju silẹ, ṣugbọn o nke'bosi ki aladugbo wa gba on. Pẹlupẹlu ibẹru ko jẹki o le fi Ejo na silẹ.

O sare gbe bọ si ode gbamgba, ko si ju ori ejo na silẹ titi ti nwọn fi lu u pa. Pẹ ti obinrin na ju silẹ lẹhin ti nwọn lu u pa tan, nṣe ni o mẹhọ. Eyi wa ṣe awọn enia loju su u wipe ọna wo ni ejo le gba wọ ile obinrin na. Ṣamọṣamọ oju ferese ni ejo na gba w'ole nitoripe ko ti lẹkun ferese lalẹ ana





**YOUR ENGINE MAY BE MORE POWERFUL THAN YOU THINK!**

I.C.A. UNLOCKS ALL THE POWER IN YOUR ENGINE

Only SHELL has I.C.A.

THE MOST POWERFUL MOTOR SPIRIT YOU CAN BUY

## Irora Ehin Didun

Ọna iwosan rẹ niyi.

Niẹ o mo wipe Kidinrin lo njẹ ki ẹhin ma dun enia? Bi ko ba si ailera fun nibẹ gbogbo idọti ara ni yio ma se dano Sugbọn bi nwọn bo nṣe tikọtikọ idọti ara ti o nwọjọ pọ a ma jẹki ẹhin-dun ni.

Aṣe egbogi DE WITT'S PILLS yi lati jẹki Kidinrin sise. Iṣẹ ti a ṣe egbogi yi fun gan niyẹn, yio wo wọn san tan, yio si mu alafia wa fun oluwa rẹ.



O to iwọn adọta ọdun ti egbogi yi ti nṣe iwosan fun enia ti Ẹhin nro. Aimọye iwe ọpẹ ni ti a ri gba kakiri aiye. Lọ ra tirẹ ni ọọbu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles



Aworan inu iwe wa yi niti Ẹni-ọla, Lord Lloyd pẹlu Iyafin S. A. Agbabiaka, iyawo ọga agba Ọlọpa-Ọba ti ilẹ Nigeria.

Iyawo Ọgbẹni Agbabiaka na ni ẹ nwo nibiti o gbe nwo bi nwọn ti nṣe iṣẹ irin nibi AFIHAN ti nwọn ṣe nilu nla London, nibiti awọn Saro gbe patẹ tiwọn si.

Awọn ilu mẹrin ni o ṣe AFIHAN na, ilu Gambia, Sierra Lone, Gold-Goast ati Nigeria.

**Let's have MUSIC! HEAR THE LATEST HIT NUMBERS**

*Read this list of popular titles*

JZ. 5825–Eyidi Hwsa/ Asew Deal J. Squire Addo.
" 5831–Onyipa Wo Dee A Oyr/Wenyina Nnhu Adze-Sampson's (Band).
" 5928–Idajo Aiyo / Ope - Iwalowa Native Air Party.
" 5960–Sabo/Lamulana) Tauridi Su'e &
" 5961–Eko Ile/O-K-K) His (Apala) Band.
" 5962–Edumare Sanu Wa / Coastal Blues) Rainbow Dandy



JZ 5963–St. Peter's Tragedy/Baba Ko Mi Lofo) Orchestral
" 5973–Bana Ware/Owei Youcha-'jaw Youths Orchestra,
" 5974 Israel/Olukun ) Kasumu
" 5975–Asiwaju/Arobieke ) Adio & His (Apala) Band.
" 5980–Adeboye II/ ) – Dauda Yinusa Ologbon Aiye) & His
" 5981–Adeke Dajo ) (Apala) Aromiso ) Band
" 5987–Awigbo/Lawal Ayinde
" 5988–Adura Owuro ) Bakare & Oluwu of Owo ) His (Juju) Band,

*Sold by all the best stores*

**"HIS MASTER'S VOICE" *Yellow Label* RECORDS**

HIS MASTER'S VOICE

Distributed by THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

## Adamodi Onijẹgi Nilu Onitsha

ONITSHA. Ọmọde obinrin kekere kan lo nṣe aisan, awọn Onișegun si sọ wipe Iya ... lero tabi Orijẹgi nikan lo le wo ọmọ na san. Iwọnyi si ni awọn ikan ti nwọn ma lo ki Orijẹgi na to jade wa.

Agọro ala kan iru ti awọn Serafu, I o Lafinda mẹfa, Ab la meje, aṣọ fu fun ọra meje, Akukọ adẹ funfun mẹta, Korẹnsi oni pupa kan.

Pelu gbogbo awọn nkan nwọnyi, nwọn dide ni iwọn jin eru Iti lọ si itiji Onijẹgi wa. Bi nwọn ti lọ ri oru ọjọ na ni nwọn rli gogo. Ṣamọṣame, aṣe bi awọn ti nlọ loru ọjọ na ti nwọn sope, ọmọ alaisan na nikanṣoṣo ni awọn nfẹ, ẹgbọn rẹ ọkunrin nyọ tẹle wọn lẹhin.

Nigbati nwọn deti odo na, Onișegun na bẹrẹ si pe oriși-riși ọfọ. Si iyalẹnu ọmọde obinrin na, o ri ti ọkunrin kan mbọwa pẹlu awo pẹrẹsẹ lọwọ rẹ o mbọ lọdọ ọmọbinrin na. Eyiyi dẹruba ọmọ na, o si salọ sile.

Nigbati ọmọ na salọ sile, Onișegun binu pada lọ sile, bẹni Onijẹgi na wa seti ebute, nibiti o gbe nko awọn ikan ti ọmọ na ko wa, beni ẹgbọn rẹ ọkunrin bara mu o si fi tulasi mu adamọdi Onijẹgi na wọ ilu wa.

Nwọn gba pọun marun ati sile mejila owo iwosan ti nwọn ti gba kuro lọwọ wọn. Ha! Kinla, Onijẹgi wọ ilu Onitsha wa.

Agbako ori ede.

## Omo kekere kan dana sun ile

IBADAN. Agbọ irohin wipe ọmọde kekere kan ti a npe ni Dick la lo tan ina ... ile kọriko kan ni abule ..., lehin ... o șișẹ bub... , lo a lẹkito.

Nigbati ..., awọn ọlọpa tẹlẹ nwọn si lu a lọ siwaju adajọ. Adajọ bere lọwọ ọmọ na ... ẹbi tabi ko jẹbi, o si dahun pe, rara! on ko jẹbi ... pe lọjọ ti a wiyi, on ko si ri abule nigbana.

Adajọ ro ọrọ na siwaju oro ẹhin, o wipe, ọmọde na ko jẹbi nitoripe, ọrọ ti awọn ọlọpa sọ, ko movan lori, o si wipe kio ma lọ ni alafia.

## Idajo Kotu Lori Iga Onisemo

EKO. Ẹṣẹ ko gbeji nibi Iga Onisẹmọ lọjọ Alaruba 8th oṣu Aug 1956 nigbati adajọ fi opin si ọrọ ẹjọ Buraimọ Onitọlọ ati Tawaliyu Onisẹmọ.

Bi ọrọ ẹjọ na ti lọ niyi wipe, nigbati ẹni ti o ti njoye Onisẹmọ w'aja, ni awọn ẹbi oloye na ba da si meji. Awọn apakan sọ wipe Braimọ Onitọlọ ni oye na tun kan, awọn apakeji ni rara, Tawaliyu ni oye kan.

Nigbati rogbodiyan ti oye na de eti ọba, o fi ara balẹ wadi ẹniti oye na tọ si, o si ri pe Tawaliyu lo to si, nipa bayi, Ọba de fila oye na fun u.

Ṣugbọn ki o to bọ lati Iga, a gbọ pe Buraimọ Onitọlọ ti lọ ko sinu Afin Onisẹmọ, o wa nleri de ẹniti yio gbe on jade. Lẹhin na a tun gbọ pe Braimọ Onitọlọ tun ṣe iwe si Kotu pe on ni ẹjọ lati ro, sibẹsibẹ Adajọ da a lẹbi, o si ni ki o jade kuro fun Tawaliyu lati wọ Iga.

Lori eyi ni ero bẹrẹ si wọ tirẹ ti nwọn nlọ ti nwọn mbọ. Nwọn si mbẹ lẹnu ọrọ na titi di ti a ti nkọwe yi lọwọ.

## Jamba Moto Ndinku

Lati gba ti a ti nkebosi pe iwaku a ti awọn dẹrẹba nwa Moto ti pọju, nwọn ko gba, bẹni nwọn ko fẹ. Ṣugbọn nisisiyi ti oju wọn ja a, ti nwọn si foju ara wọn ri awọn ohun ti o nṣẹlẹ olukuluku wọn ti sunra ki, nwọn si nṣe bi o ti tọ.

Awọn akọwe kotu papa sọ pe ẹjọ o ṣe Mọto, ko ṣe Mọto ko tun pọ ninu kotu mọ. Lati oṣu Jan. si ibẹrẹ oṣu April, iye ẹjọ Mọto ti nwọn ṣe ni Kotu ko ju iwọn ọgbọn lọ.

Ni agbegbe Ibadan si Ọyọ Ibadan si Abẹokuta ati si Iwo, iye jamba Mọto ti o ṣẹlẹ lati ibẹrẹ ọdun wa ie mejidilọgọta.

Ninu jamba, wọnyi, meji lo burnju, ti enia mejidinlogun farapa pupọ.

## Talo se e?

Lọjọ kan, agbẹ kan lọ si oko lati lọ roko bi o ti nroko lọwọ, bẹni kokoro kan fo wa o ba le e ni oke oju, o si ta a.

Lẹsọ kanna, oju oloko yi ti wu, o si nro o. Oloko na wa lọ ọba lọ, osi fi ẹjọ sun wipe, jẹjẹ ni on nroko, ki kokoro kan to wa ta on.

Ọba bere wipe tani nwọn ropo o le ṣe iru iṣẹ bẹ, nwọn dahun pe ayafi Agbọn ati Oyin. Ọba si ranṣẹ pe awọn mejeji. Ọba bi nwọn lere, tani ta oloko bayi. Agbọn ni ko nṣe on, Oyin ni ko nṣe on.

Eyi na lo di owe ti nwọn npa bayi pe, Agbọn nsẹ, Oyin nsẹ bẹni oju oloko lo wu kubọ-kubọ yi, talo ṣe e ?.


## Ogun Aran (Fjo Inu)




Aradan Worm Expeller je ogun aran pataki fun omode ati agba ọkunrin ati obinrin. Ra igo kan lati ya gbogbo awọn aran buburu ti o nba o ja n'inu danu. Bi o ti npa aran, beni o npa eyin wọn. Wa ra t re ki o to tan. Igo kan je 2/6d. Owo-Ọkọ si je 1/-.
THE EGBA TRADING ARADAN STORES,
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebute Metta.

## KEKE BASIKULU TO LAGBARA JU





Kanti wipe awọn irin ise KEKE PHILLIPS gegebi awọn ohun ti afi nda KeKe dura. ibiti a ngbe ese le ati bawonrì, je eyiti olokiki kakiri aiya, wipe tiwa lo lagbara julo ti osi dara. – KeKe Basikulu ti Phillips ti afi irin ise Phillips se je eyiti Kolegbe Ni Gbogbo Agbaiye.

Malo Basikulu Ti **PHILLIPS**

KEKE BASIKULU TI AFI IRIN TUTU SE

... AWỌN ... ALARABARA ...
PHILLIPS CYCLES LIMITED · BIRMINGHAM · ENGLAND


Printed & Published by The Union printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 2...